OWE

Oju ni a
mo aisi-
po, enu
ni a nmo
siyo, obe
i ko ni
ran idu-
o ni amo.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO ṢE WI LEJO

Asoje

Igbali-
y e, aiye
ko l'ayo-
le.
B'ole lo-
ni o le ro
lola.

VOL. XIV No 818 LAGOS. SATURDAY FEBRUARY 24. — MARCH 2. 1962. KOBO MEJI (2D)


# OBA ADELE, KEJI, FE RO AWON OLOYE MARUN LOYE NILU EKO.

EKO Ija kan mbọ! ọtẹ titun fẹ bẹ silẹ larin ọba Eko ati awọn Oloye re !!

Irohin ti o ta siwe lati fẹrẹẹ ninu ọsẹ yi ni wipe Ala'yehuwa Ọlọla Adeniji Adele, Oba ilu Eko fe rọ awọn Oloye marun kan loye ninu awọn Oloye rẹ nitoripe nwọn ko ṣe tire, gegebi a ti gbọ ọrọ na si.



ỌBA ADELE KEJI

A gbọ wipe Alaiyeluwa Ọba Eko ti fi esun awọn Oloye na siwaju Alaṣẹ ilu Eko nwọn si ti fi iwe kesi awọn Oloye na lati ile iṣẹ Alaṣẹ ilu Eko, lati gbọ tẹnu wọn.

Awọn Oloye ti a gbọ wipe ọrọ na kan ni Oloye Aminu Kosọkọ, Asajọ, Ọlọja Ereko, ilu Eko, Oloye Oloregun, Oloye Olumẹgbọn, Oloye Ọbamikoro ati Oloye Onilẹgbalẹ.

Ẹnyin alagba ilu Eko, owe kan sọ wipe "Agbalagba ki i wa l'ọja, ki ori ọmọ titun wọ" O ṣe bi owe, a ẹrẹ-f'oji ! Alaiyeluwa Ọba wa ati ẹnyin sa-



OLOYE AMINU KOSOKO
(Asajọn Ọlọja Ereko)

raki Oloye wa, ẹ fi ẹegun Ololo too. Ẹ ma jẹ ki a tun bẹrẹ rogbodiyan Ọtẹ titun nilu Eko.

A fi wesika wa yi bẹ Oba ati awọn Oloye rẹ nitoripe ọrọ ọtẹ ki i ṣalai bi "Ile bi Adubi" Lọmọ nilu Eko, nigbati o ba te sile.

Ẹnyin agbalagba na ni ẹ fi ve wa wipe 'Kekere ni nwọn ti npa ẹckan 'roko, ... [illegible] b o tu d'agba tan, apa ko ni ka mọ".

(Owe ni o, ẹ bọrọ f'oji)

## Ay'orunbo Miran.

Bi ilu Amerika ti tun ngbero lati ran ena miran lọ si ilu Oṣupa, beni irohin jade lati ilu Faranse wipe Ekati ati Ologbo ni awọn yio koko ran lo silu Oṣupa lipari oṣu March, 1962.

# OWO OLOPA TE OGA'GUN MAU MAU NILU KENYA

KENYA—Awọn Ọlọpa ilu Kenya so wipe lehin ti awọn ti fi ibọn ja paraku ninu igbo Imenti lese oke giga ti o wa nilu Kenya, ni ọwọ te Ọga'gun awọn janduku enia ti nwọn npe ni Mau Mau.

Ninu igbo Imenti yi ni nwọn ti nlo fi awọn enia eya Meru mu aje ninu odun tokoja, o le ni egberun enia ti oro na kan nigbana.

Ẹnikan ti nwon tun fura si wipe onijongbon eria ni, nwon mu pelu Ọga'gun lehin ija ogun na.

Agb'orọ so won sọ wipe ijo meje ni awon janduku adajongbon sile ti o ti wa ninu igbo na ti nwon ti nfa ijongbon lojo ti o pe nisisiyi.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA

ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger : London
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH

# MARY BIGNAL GBAWE IPE



Omobirin ti a rwo ninu aworan yi ni Mary Bignal, osere idaraya ti o nka iwe ipe ti o ri gba lati owo Ọlọlajulọ ọmọba Philip ti o fi pe lati wa danrawo fibi ere ije ti nwon yio ṣe nilu Rome.

Mary jẹ ọkan ninu awọn adota enia ti a ṣa yan fun elere ije ti Gẹsi ti awon ti ri iwe gba wipe yiyan ti wọn ti daju gegebi iwe ti Ọlọlajulọ ọmọba Philip ti o jẹ Alakoso Igbimọ Osere idaraya ilẹ Gẹsi ti f'ọwọsi.

## Jamba Ekun'mi S'ele Nile Jamani

HAMBURG - Awọn enia ti awọn nṣe iṣe igbala awọn ti omi ti o kun akun-ya wọlu ṣe ni jamba nika Gusu ilu Humburg, gẹgbi awọn iwe irohin ti ṣe apejuwe wipe awọn enia ti ekun-omi na ko lọ yio to awọn irinwo si ẹdẹgbẹta enia, ti tun bẹrẹ iṣẹ wọn ni ọjọ Atalata ọsẹ yi.

Awọn enia ti nwọn ti mọ wipe nwon ti ku sinu ẹkun-omi na ni ipari ọsẹ tokoja jẹ ẹta-le-logbọn le-ni igba enia (233). Ṣugbọn wọn ni igbagbọ pe ọpọlọpọ enia ni wọn wa ninu ahere ati ọgba nla ni Wilhemsburg, ibi ile iṣẹ ti iwọn ọkẹ mẹta enia gbe wa larin odo Elbe ti omi na ka mọ.

Bi omi na ti nfa bọni ẹgbẹgbẹrun enia npada si ile wọn ṣugbon ni apa gbereko, o si ku enia bi ọkẹ kan ti nwọn ko ri ẹna gba fun omi ti o kun wọ ile wọn.

O fẹrẹ to ọkẹmẹta enia ole-ẹdẹgbajọ (£75,000) ti o di alaini ile lori.

Lọwọ jamba ẹkun-omi, Oluwa rere gba wa.

# ELETI - OFE D'ARABA

E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe.

# BOBBY, OSERE IDARAYA



Eniti anwo ni u aworan y' ti Bobby Brigtwell ti o jo okan ninu awon eebe elere idaraya ti yio ba won n ura re nisiyi nile Rome.

A si ni igbokele wipe yio yege ninu ere s'sa na yio si gba ami Golu bo wale fun ohun iyin ere na.

# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ENITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI EGUN TI ONIṢOWO LE SE TI ỌJA RE YIO FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu**

**Iwe Irohin Eleti - Ofe**

# Onijibiti W'ewon

IBADAN - Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Alhaji Alhaji Muhammadu ti o pa ara rẹ ni Awo atọlẹwo ni Ketu ṣa korikọ ẹwọn ọdun meji abọ mọ lara loni ri esun wipe o fi jibiti gba owo ọdunrun ọ(ẹẹ)o din merinla (£286) lọwọ Ọgbẹni Job Igbojọẹnu.

Ogbẹni Igbojẹunu sọ wipe ni ọjọ keta oṣu January odunni ni Salu Yaro fi Muhammadu han on ṣegebi Mẹlẹda owo, ti o mọ owo di pupọ, nigbati o si mu da on lẹju pe on yio sọ ọdun-run-din-merinla ponun (£286) di ẹgbaa ponun ni on fun ni owo na.

Ṣugbon ko ju abọ wakati lọ ki iye-iau on to fi, ni ori wa fura wipe jibiti ni nwọn lo fun on yi, on si peda lọ sọ ọ Muhammadu tati gba owo on pada ṣugbọn nigbati on de ibẹ, Muhammadu fa ibinu yọ buruku-ẹuruku, o si ma ada ti fi ṣa o...

Nigbati nwọn rojọ na siwa-ṣẹhin, adajọ ṣa Alhaji Muhammadu si ẹwọn ọdun meji-abọ.




NIGERIAN TOBACCO COMPANY LIMITED

# KEKE OLOGERE ALUPUPU ALATUPA MEJI




Omobinrin ti o ngun kẹtẹ Ologere Alupupu ti, o ni oju atupa nla meji ti itanşon imọle re fere le tiran de idaji ibuşọ ni oru, ti o si le rin iwọn adọrin ibuşọ ni wakati kan ni a nwo ninọ aworan yi.

# OLU BURUKU AJE RORUN

Ondo – Irohin ti a ri gbọ niti ọkunrin agbẹ kan ti o mu esu bọ lati oko rẹ wipe ki iyawo on si lọbẹ. Iyawo si se Olu na, ọkọ iyawo ati ọmọ wọn ọkunrin ni awọn fi jẹ iyan lalẹ ni Olukuluku lo un

Sugbọn nigbati o di oru ọganjọ ọiọ na, iboşi inu rirun awọn meteta ni o ji awọn ara ile, ti ọrọ na fi di işẹ fun awọn aladigbo ti nwọn ngwanju lati toju wọn, ti nwọn, şugbọn awọn meteta ti di eku ọrbi ki ilẹ ọjọ keji tomọ.

Ki Oluwa tere şọwa lọwọ atẹnijẹ ti kọgọ'ogun

# ITAN OMO IYA-METTA

Ni igba laila, Baba kan ati Iya kan wa, won bi omo metta, nigbati awon omo na dagba tan, Baba won bi ekinni pe ise wo ni iwo fe se? o daun wipe on yio se ise aso rirun, Ekeji ni on se ise ona yiye, Eketa, iyen abikehin, o ni on yio ise ogun.

Nigbati ejo ti won ni lati fi odo baba won silo pe, awon meteta jade nwoo rin lo, nigbati won de orita metta, won wi fun ra won pe lehin odun metta, ti awon pade ni bi yi.

Onikaluku mu ona tire por, ti won bi lo, ni nigbati nwon pinya tan, onikaluku lo si ilo ti owu un is eti o wu won.

Eyi ti o ni on yio kose aso riran, o ko ise yen o mọ dada beni eyiti o ni on yio ko ise ona yiye, o ko o mọ dada beni ek ta, aburo o ko ise oogun o fere folori gbogbo won si nri ise dada.

(*Wo* yoku loju ewe karun)

YORUBA CHALLENGE

March—April 1962

TI JADE FUN TITA.

Okun Fun eko Ajinde, itan ati irohin. Awon aworan inu re fanimora. Oju iwe re pe 24. Tete ranse tire. 4d pere fun iwe kan.

## ẸJỌ AWỌN OBINRIN OJA

EKO - Adajọ Ọgbẹni F,O.M. Atako, ni agbọ wipe o ti da ẹjọ awọn obinrin ọja ti nwọn fi sun ẹsun apejọ ti ko tọ suna ati ipade ti nwon npe lai gbaşẹ pada si Ọga Alakoso ẹjọ Ijọba fun ayẹwo.

Adajọ wipe bi Ọga Alakoso ẹjọ Ijọba (Director of Public Prosecutions tba gba lati mu ejo na kuro ni kotu, yio tẹ on lorun. Bi o ba si kọ, lẹhin ni o ba ti ri ododo ọrọ na gẹgẹbi o ti wa niwaju on yi, nigbana, awọn bi ẹdunrun enia ni nwọn yio ma mu wa si Kotu niwọn iba ti Kotu ba le gba lati şe ẹjo wọn ati ẹri ti nwon yio fi ba wọn şe ẹjọ. Kotu yi ko le gba gbogbo wọn pọ lẹkan.

(Wo yoku loju ewe karun)

# EJO AWON OBINRIN OJA

(O bere loju ewe kerin)

ni Ogbeni Alatako so wipe ejo ti Iha Gusu Afrika on ko ka kun nwon igbati ko ti si iwa jagidijagan larin won. Adajo bere lowo ege olopa Alatako won bi awon obinrin n a je ako si igbati ile ete ? Oga ol pa Ogbeni B.H. E omi dahun pe ko si ohun ti o jo be rara. Koto bu s'erin o tin so wipe on pe awon obinrin na ki nwon be on kalo si le o epa Station) ki nwon le ba Gomina Gbogbo-gbo soro.

Adajo sun ejo na si waju.

# ITAN OMO IYA-META

(O bere loju ewe kerin)

Nigbati ojo ati odun ti won da fun ara won pe, onikuluku gbera ni ilu ti o wa lati wa pada si orita meta ijosi ti nwon ti pinya.

Aburo lo koko de orita, won reti titi ko ri won o ba bere ise ti o ko lati mo bi nwon mbo bi nwon ko wa, ati lati mo boya won ti ku ni, o si ri ninu opan ifa re pe won ko ku, o si tun ri pe awon m ejeji ko ni pe de, o si tun ri ninu opan ifa kanna pe egbon awon ni yio kehin de.

O ep ri ifa yi tan ni abitele de, ko pe pupo ni egbon won de.

(Iyoku di ose Cominj.)

## OTITE TITUN TILU FIJI




OTITE titun ti M'chael Goaman sese se fun Ijoba ilu Fiji ni a nwo ninu aworan yi pelu aworan Alaiyeluwa Oba Obinrin ilu Oyinbo.


NO. 34.

**Federation Of Nigeria**
**THIRD DEVELOPMENT LOAN**

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:—

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966—to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986—to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

W. A. TIBBLES
General Manager

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.


# OLOPA NWA ADAMODI DOKITA

OKIGWI—Awon olopa nwa okunrin kan ti o pe ara re ni Dokita Orji, lati iwe ase lati fi se ise, ti o si se ise obe fun Ogbeni Agim Nwosu agba ti o ngbe ilu Umualumaku ni agbegbe Okigwi laipe yi ti oluware ku mo lowo.

Ogbeni Nwosu ni a gbo wipe aisan kun-sinu mba ja, nigbati adamodi Dokita yi se ise fun u ni o ku mo lowo ni ojo kejila osu Febru ry yi.

Lesekese ni okumorata Dokita Orji na fi ese fee. Awon olopa nwa lowo.

## Abileko Obinrin Jebi Esun EwE Taba Igbo

IKEJA—Obinrin abileko kan ti oruko re nje Seri Kike, bi omo odun meta-din-lo-gbon ti o ngbe NO. 65, Opopo Ona Ikorodu, ni Adajo Kotu Ikeja sa konko owo ponun mewa ati sile mewa mo lara tabi ewon osu meji bi ko ba ri owo san lori esun ti awon olopa fi sun wipe won ri ewe-taba Igbo, ogoji ti nwon ti di lowo re.

Ninu idajo re ni Adajo agba, A.A. Adesigbin ti so wipe oro ewe-taba Igbo npo si ni ilu yi, nitorina, ki o lo san'wo tabi ki o lo s'ewon.




## E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE LOSOSE

## Erin Te Enia Meji Pa Nitosi Ibadan

IBADAN – Irohin ti a ri gbo lati ilu Ibadan ni ipinle Iwo-Orun ni wipe erin te awon enia meji pa.

Nwon so wipe okan ninu won ni o mu erin na binu nigbati o ja ewe senu ti o si nkegbe. Ibu si bi eranko na depo ti o fi owo-ija re na, o si gbe sanle, o wa te ni atepa.

Ni abule Ilupeju itosi Abeokuta ni a ti gbo iku okunrin agbe kan ti o nje Samuel Sobayo wipe o ti ku sinu igbo kan ni ibudo Bakatari, iwon buso mejo silu Ibadan.

Nwon i. Sobayo npa epo igi kan ati egbo re lati fi se egbogi, ni erin kan ba kolu lojiji o si pa bambam.

## Ojo Isinmi Odun Musulumi, 1962.

EKO-- Ikede Ijoba ti o jade nilu Eko ni ojo Alaruba (Wednesday) ose yi fun ojo isinmi odun awon Musulnmi ti ao se ninu odun 1962 yi.

Ojo meji fun itunu-Awe -Id-el-Fitri, ojo Alaruba ojo keje ati Alamisi ojo kejo osu March, 1962.
Ojo meji fun odun Ileya - Id-el-kabir. Ojo Monday ojo kerinla ati Tuesday ojo kedogun o s u May, 1962.
Ojo ibi Anabi Muhammad, ojo Monday, ojo ketala osu August, 1962. (Maulud Nabiyi).

Awon ojo wonyi ni Ijoba yan sile fun ojo isinmi odun Musulumi jakejado ile Nigeria fun odun 1962 yi.

Printed & Published By The Union Printing & Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23370